# BÍBỌ̀ JESU LẸẸKEJI

**Luku 12:35-57**

**ẸKỌ 45 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ohun ti mo wi fun nyin, mo wi fun gbogbo enia, Ẹ mã ṣọna" (Marku 13:37).**

### Iyawo Kristi

Ni ọjọ kan lai pẹ, Oluwa wa yoo yọ ninu awọsanma loke lati pe iyawo Rẹ̀ si ibi Ase-alẹ ti Igbeyawo, eyi ti yoo ṣẹlẹ nibi kan ninu awọn Ọrun. Iyawo naa yoo jẹ awọn wọnni ti wọn jẹ Ijọ Akọbi ti o ti pese ara wọn silẹ fun iṣẹ̀lẹ yii. Bibeli ṣe alaye ti o yé ni yékéyéké ohun ti eniyan ni lati ṣe ki o ba le pẹlu ẹgbẹ aṣẹgun ti yoo fi aye silẹ ti yoo si goke lati pade Ọkọ-Iyawo. O ṣe e ṣe fun gbogbo eniyan lati pẹlu wọn.

Ko si ẹni ti yoo gbọ ipe si Ase-alẹ Igbeyawo afi awọn ti wọn ti pese ara wọn silẹ, awọn ti wọǹ si ti "fọ aṣọ wọn, nwọn si sọ wọn di funfun ninu Ẹjẹ Ọdọ-Agutan." Yoo jẹ ohun iyalẹnu fun awọn ẹlẹṣẹ nigba ti gbogbo awọn Onigbagbọ́ tootọ ba parada lojiji. Jesu le de lati wa mu Iyawo Rẹ̀ lọ nigbakuugba -- o le jẹ nisisiyii -- ṣugbọn awọn eniyan ti wọn n mura silẹ ṣi kere niye. Ninu ẹ̀kọ́ oni Jesu n sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe baale ile i bá mọ wakati ti ole yoo wá, oun i ba ti maa ṣọna, ki ba si ti jẹ ki a lu ile oun já. Jesu ti fun wa ni ikilọ pe Oun o de gẹgẹ bi ole loru (1 Tẹssalonika 5:2), nitori naa nigba gbogbo ni a ni lati maa wa ni imurasilẹ.

### Biba Ọlọrun Rìn

Ki ẹnikẹni to le wa ni imurasilẹ fun bibọ Jesu, ki i ṣe kiki pe ki o ri igbala, pe a dari ẹ̀ṣẹ rẹ ji i, ki a sọ ọ di mimọ́, ki o di alai leeri nipa iṣẹ oore-ọfẹ keji; ki o si ni ifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni, aṣọ igbeyawo nì; ṣugbọn o ni lati maa ba Ọlọrun rìn timọtimọ ni gbogbo akoko, gẹgẹ bi Enoku ti ṣe. A pa Enoku lara dà, a si mu un lọ si Ọrun lai kú, gẹgẹ bi a o ti ṣe fun Iyawo Kristi ti o wà ni aye nigba ti Kristi ba pada bọ̀.

A ni lati ba Ọlọrun rìn timọtimọ to bẹẹ gẹẹ ti iṣe wa, ilepa wa ati igbesi aye wa paapaa yoo maa tọka si bibọ Oluwa. Bi a ba fa sẹyin ni wakati kan ti Jesu si de ni wakati naa a o padanu ohun gbogbo. Jesu n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ ki o maa ṣọna ni gbogbo akoko fun bibọ Rẹ̀. Iwọ wo iru ipo ti iwọ yoo wà ki awọn iyoku ninu ẹbi rẹ ti i ṣe Onigbagbọ́ fi aye silẹ ki o si ku iwọ nikan ṣoṣo lati la ipọnju nì kọja. Fi iru ipo buburu yii we ogo ti o wà ninu pe ki a gbà ọ si oke ki o si bọ lọwọ gbogbo wahala ati ijiya ti yoo ṣẹlẹ ni aye.

### Ti A Pamọ Pẹlu Jesu

Ifarahàn Jesu yoo jẹ ipa meji nigba ti O ba pada de: ni akọkọ yoo dé si inu awọsanma, bẹẹ ni oofa nla yoo fa Ijọ aṣẹgun si ọdọ Rẹ̀. Ipọnju ti o buru rekọja n bọ lori aye, igba wahala ti iru rẹ ko i ti ṣẹlẹ ri, Oluwa kò si fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ ki o jiya. Nitori naa ni O ṣe n bọ wa gba awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ soke. Yoo si wi pe: "Wá, enia mi, wọ̀ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi ẹnipe ni iṣẹ́ju kan titi ibinu na fi rekọja" (Isaiah 26:20). Iyawo Kristi yoo wọ iyẹwu lọ loke, lati joko nibẹ nibi Ase-alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan (ti i ṣe Jesu), Jesu tikara Rẹ̀ yoo si maa ṣe iranṣẹ fun wọn. Nigba naa ni a o pin èrè iṣẹ ti a fi otitọ ọkan ṣe ni aye. Ki yoo ha jẹ ohun iyanu lati wà nibi ase ologo yii pẹlu Jesu?

### "Ẹ Jẹ ki A Yọ̀, Ki Inu Wa Ki O si Dùn"

Yoo jẹ akoko inu didun fun awọn ọmọ Ọlọrun nigba ti Ọkọ Iyawo ba de lati wa mu wọn lọ. Nigba ti Johannu Ayanfẹ wà ni Erekuṣu Patmo, o ri iran ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ ti n bọ, o si kọ akọsilẹ:

> **"Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: nitoripe igbeyawo Ọdọ-agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan.**
>
> **"On ni a si fi fun pe ki o wọ aṣọ ọgbọ wíwẹ ti o funfun gbõ: nitoripe aṣọ ọgbọ wíwẹ ni ni iṣe ododo awọn enia mimọ́.**
>
> **"O si wi fun mi pe, Kọwe rẹ̀, Ibukún ni fun awọn ti a pè si àse alẹ igbeyawo Ọdọ-Agutan" (Ifihan 19:7-9).**

Awọn ti o ti ku gẹgẹ bi aṣẹgun yoo ni ipin ninu iṣẹlẹ nla yii: "Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun" (1Tẹssalonika 4:16, 17).

### Ifarahàn

Nigba ti a ba gba Iyawo Kristi kuro ni aye yii, ipọnju nla ni yoo bẹrẹ yoo si le kikankikan. Iyawo Kristi yoo maa gbadun ase igbeyawo nigba ti awọn ti wọn kọ̀ lati mura silẹ fun bibọ Oluwa yoo maa jiya labẹ akoso Aṣodi-si-Kristi.

Nigba ti Ase-alẹ Igbeyawo nì ba si pari ni ipọnju naa yoo si pari pẹlu. Lẹyin eyi ni Jesu yoo tun pada de, lakoko yii pẹlu awọn eniyan Rẹ̀ mimọ́, “gbogbo oju ni yio si ri i, ati awọn ti o gún u li ọ̀kọ pẹlu; ati gbogbo orilẹ-ede aiye ni yio si mã pohùnrere ẹkún niwaju rẹ̀” (Ifihan 1:7). Wọn o maa pohùnrere ẹkun nitori pe ẹ̀rù yoo ba wọn lati pade Jesu ni idajọ.

Eyi ni akoko ti Enoku sọ tẹlẹ pe, “Oluwa mbọ̀ pẹlu ẹgbẹgbãrun awọn enia rẹ̀ mimọ́, lati ṣe idajọ gbogbo enia (Juda 14, 15). Wọn o gun ẹṣin funfun, nitori a kà ninu Ifihan 19:14 pe, “Awọn ogun ti mbẹ li ọrun ti a wọ̀ li aṣọ ọgbọ wiwẹ, funfun ati mimọ́, si n tọ̀ ọ (Jesu) lẹhin lori ẹṣin funfun.” Njẹ o le fi ọkan wò bi eyi yoo ti ri? Jesu tikara Rẹ̀ yoo wá lori ẹṣin funfun, bi O ti n bọ lati wa ṣe akoso aye pẹlu ọpa irin, ni itan Rẹ̀ ni orukọ kan ti a kọ, ỌBA AWỌN ỌBA, ATI OLUWA AWỌN OLUWA; lẹyin Rẹ̀ ni awọn eniyan mimọ́ ti o ti wà nibi Ase-alẹ Igbeyawo ni yoo maa bọ̀, lori ẹṣin funfun bakan naa. Wọn o ni ipin ninu ṣiṣe akoso ayé. Jesu ni awọn miiran yoo ṣe akoso ilu kan, awọn miiran meji, awọn miiran marun-un, tabi mẹwaa.

**Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun**

Kristi yoo gbé ijọba kalẹ ni aye yii, awọn eniyan yoo si maa gbe igbesi aye wọn lọ bi ti atẹyinwa kiki pe ohun gbogbo yoo wa labẹ akoso Kristi. A o mu ègún kuro, awọn eweko yoo si gbe ẹwà titun wọ̀. Aye yoo dara lọpọlọpọ lati gbé inu rẹ. Awọn eniyan mimọ́ ti a ji dide yoo ni ara ologo iru eyi ti Jesu ni lẹyin ti O jinde kuro ninu oku, nitori pe Oun ni “akọso;” lẹyin eyi awọn ti i ṣe ti Kristi ni bibọ Rẹ̀ (1 Kọrinti 15:23). O le jẹ, O si le mu, nigba ti O wá ninu ara ologo nì, sibẹ O le lọ ninu afẹfẹ lai jẹ pe ẹni kan ri I, O le gba ẹnu-ọna ti a ti ilẹkun rẹ wọle, ki O si fi ara han laaarin awọn eniyan Rẹ̀. “Nigbana li awọn olododo yio mã ran bi õrun ni ijọba Baba wọn” (Matteu 13:43).

A ri i bayii pe bibọ Oluwa pin si ifarahan meji: akọkọ ni si inu awọsanma lati mu Iyawo Rẹ̀ lọ nigba Ipalarada, ati nigba keji yoo pada pẹlu Iyawo Rẹ̀ yoo si sọkalẹ sori ilẹ aye, ẹsẹ Rẹ̀ yoo si duro lori Oke Olifi nibi ti O ti goke lọ si Ọrun (Sekariah 14:4, 5). Nigba **Ipalarada,** awọn eniyan mimọ́ nikan ni yoo gbọ́ ipe Rẹ̀; ṣugbọn nigba Ifarahàn “gbogbo oju ni yio si ri i.” Ipalarada yoo ṣẹlẹ ṣaju Ipọnjunla, **Ifarahan** yoo si ṣẹlẹ nigba ti Ipọnjunla ba fẹẹ pari. Ifarahan si le ṣẹlẹ nigbakigba. “Nitorina ki ẹnyin ki o mura silẹ: nitori ni wakati ti ẹnyin kò ro tẹlẹ li Ọmọ-enia yio de” (Matteu 24:44).

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni Ipalarada?

2 Awọn wo ni a o gbà soke nigba Ipalarada?

3 Ta ni a fi Oluwa wé nigba Ipalarada? Ta ni a fi Ijọ we?

4 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun ni akoko ipọnju?

5 Awọn wo ni yoo wá pẹlu Jesu nigba ti O ba dé lati ṣakoso ayé? Ṣe apejuwe dide wọn.

6 Inu rẹ yoo ha dùn lati ri Jesu?